Bibeli fun awon omode

# Olorun dan ife Abrahamu wo



Ikosile gba owo: Edward Hughes

Ayaworan: Byron Unger; Lazarus

Olu'lo: M. Maillot; Tammy S.

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2018 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.



Li asale ojo kan, Olorun fun Abrahamu li ase kayefi Lati mo boya Abrahamu feran omokunrin re, Isaki ju Olorun lo.


"Mu omokunrin re, Isaki, ki ofi rubo ina", Olorun p'ase. Fi Isaki se ore ke? Fi omo re rubo ke? Eyi je ohun to soro fun Abrahamu. O feran omo re daradara.

Sugbon Abrahamu ti ko Lati gbekele Olorun nigbati koye. Li kutukutu owuro ojo keji, ogbera Lati losi ori oke irubo pelu Isaki ati eru meji.



Ki Abrahamu to jade,
omu igi idana dani.
Abrahamu pinu Lati
gbo ti Olorun.





Li ojo keta won sumo ori oke na. Abrahamu so fun awon eru re wipe “eduro nihin,

awa yio lo lati sin Olorun, a o si pada wa si odo nyin”.

Isaki bi Baba re, "aguntan irubo da, Baba a mi?" Abrahamu daa lohun: "Olorun yio pese aguntan fun ara re".



Awon mejeji wa sibiti Olorun ti yan, Abrahamu te pepe, osi to awon igi irubo si Olorun.



Abrahamu ti te opolopo pepe tele ri sugbon, pepe yi je ohun to nira fun.



Abrahamu mu Isaki. Ode lowo-lese, osi te omo re tofe si ori pepe. Se Abrahamu yio gboran si Olorun lati fi omo re kan soso rubo bi?





Beeni! Obe na sana nigbati Abrahamu gbe soke. Iberu lemaa mu li okan sugbon Abrahamu mo wipe ohun ni lati se gboran si Olorun.



Logan,
Angeli
Oluwa ke li
ohun rara,
“Dawoduro!
Nisisiyi, mo
mo wipe o
beru Olorun.
Iwo ko da
omo o re kan
soso si kuro
lodo mi”.

Ni kete, ori eran agbo ninu igbe to wa ni itosi, Abrahamu tu Isaki sile, osi fi eran agbo rubo dipo o re. “Olorun ti pese gegebi Baba mi tiwi”, Isaki ro eyi ninu ara re.



Nigbati Baba ati omo re nsin Olorun, Angeli wi fun Abrahamu wipe, “Ninu awon omo re, gbogbo orile-ede ni yoo di alabukun fun nitori wipe o gboran.” Li ojo kan, a o bi Jesu nipase okan ninu awon iran Abrahamu.



Abrahamu ati Isaki pada si Ile. Lehin saa kekere, Sara aya Abrahamu se alaisi. Abrahamu ti se oloogbe aya re, Isaki pelu ti se oloogbe Mama re.





Lehin isinku, Abrahamu ran erukunrin re agba lati wa aya fun Isaki. Erukunrin na lo si ilu Abrahamu lati lo wa aya laarin awon ebi Abrahamu.

Erukunrin na bere ami kan lowo Olorun. “Jeki iransebinrin ti oba bu omi fun awon ibakasie wonyi je eniti o yan li Aya fun Isaki”. Logan, Rebeka bu omi fun awon Ibakasie. Oje okan ninu awon ebi Abrahamu. Erukunrin na si mo daju wipe Olorun ti gbo adura a re.



Rebeka fi awon ebi re sile lati fe Isaki gegebi oko re. Rebeka tu Isaki ninu Lehin iku Mama a re. Isaki feran re lopolopo.



Olorun dan ife Abrahamu wo

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Genesisi ori mejilelogun titi de merinlelogun

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi 119:130

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun
iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe:
Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo!
Johannu ori keta ese kerindinlogun.